ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ...

VOL. XIV NO 826 LAGOS SATURDAY JUNE 30, — JULY 6, 1962, KOBỌ MEJI (2D)

# Baba Kan Fe Fi Tubu

## Se Ile-gbigbe O Ni Igbadun Wa Nibe

ABAKALIKI—Li ọjọ Iṣẹgun (Tuesday) ti o kọja yi ni ariwo ta ninu ọgba awọn ẹlẹwọn lẹhinti awọn ẹlẹwọn na ti jẹ onjẹ owurọ wọn tan ti awọn ọga ile-ẹwọn na tọ ikan ninu awọn arufin na lọ ti orukọ rẹ njẹ Aheze Udu, ti nwọn ni ki o ma lọ si ile rẹ.

Onirohin wa ni Ọgbẹni Udu tiṣe agbẹ ni abule Ezamugbo ki nwọn to ju u s'ẹwọn niwọn bi ọdun keji sẹhin, ba fi ake kọ'ri; o ni on ko lọ. Nwọn fi l'ogun, nwọn fi l'ọgbọn, o ni ṣe awọn ko mọ wipe on ti fi ibẹ ṣe ile-gbigbe ni?

Awọn olusọ ile-ẹwọn na fa a, nwọn wọ ọ, o kọ jalẹ o ni on ko sa ni jade nibẹ. O ni gbogbo igbati on ti wa l'ẹwọn l'ọfe ni on njẹnn, gbogbo nkan inu oko on ni o ti jona, nibo ni nwọn fẹ ki on ti ma ri onjẹ jẹ lasiko-lasiko bi ti ọgba ẹwọn yi.

Awọn ọlọpa ni nwọn kesi, ti nwọn ru ọkunrin na jade kuro lọgba ẹwọn ni ọsan ọjọ na.

**LAGOS RACE CLUB**

JUNE MEETING, 1962

Due to heavy rainfall, the Third Day Race for June Meeting fixed for Saturday 23rd June, 1962 has been postponed until Saturday the 30th June, 1962 weather permitting.

C. H. MILLER,
Secretary.

**THE NATIONAL BANK Of Nigeria Limited**

Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £3,160,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria

HEAD OFFICE
80/88, BROAD STREET, LAGOS NIGERIA
28 Branches Throughout Nigeria Including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE, OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA, ILARO, BENIN-CITY WARRI, SAPELE, ABA, KANO, ZARIA, JOS,

LONDON OFFICE
15, THROGMORTON AVENUE, E.C.
Manager F. O. Tyrrell

Telephone London Wall 4303
Cable & Telegrams Natbaniger : London
Head Office Representative in London
E. Akinwumi Doherty,

CORRESPONDENTS
NEW YORK, PARIS HAMBURG

**STAR LAGER**

OFF - LICENCE SELLING PRICES
STAR large size bottle ... 2/9
STAR small size bottle ... 1/7

Selling price at Bars, Hotels and other on - licence premises
STAR large size bottle ... 3/-
STAR small size bottle ... 1/9

# Awo Irawo

## Eyi ni awon nkan ti yio sele si o ninu ose ti mbo.

AQUARIUS (Jan 22–Feb 20) Wa ri ere le nmu a nra a nta, sugbon ojo kan a sele, ti o ko ba f'ogbon yanju e a di koko die fun o.

PISCES (Feb 21–Mar 20) Mase ba enikan ja. Lati bi ojo meta wa okan re ko p'ayida, daraya, gbogbo re ni a gbonu.

ARIES (Mar 21–April20) Bi o ko ba f'obinrin nile ojo Monday ti mbo dara fun o lati se'ju s'obinrin.

TAURUS (April 21–May 20) Ojo Monday ati Tuesday ti mbo yi dara fun o pupo. Maṣe pe nita lora ki o si fidi mole die.

GEMINI (May 21–June 21) Ṣiṣe kara-kara wa ri ere nibe; ma si se yi ise-owo re pada rara.

CANCER (Jun 22–July 23) Enikan ninu awon ebi re yio wa ki o, ore re kan yio ba soro aṣiri, ki o maṣe jaa tile.

LEO (July 24–Aug 22) Nkan kan a ma e nawo aburadi kan, eyi a si ko rewesi ba o fun igba die: wa gburo olufe re kan si daradara.

VIRGO (Aug 23–Sept 23) Okan ninu awon omo re a ṣe aisan ranpe kan, tete mu lo si ile dokita Aye wa fun e lati ri owo se lose yi.

LIBRA (Sep 24–Oct 23) Oga re kan nṣe akiyesi iṣe re lowo–lowo yi; owo rere ti o ba hu si awon ore re lose yi ni yio je ki o ri oju-rere won.

SCORPIO (Oct 24–Nov 22) Boya olufe re le ṣe o ni ose yi, maṣe binu, gbogbo re a yori si daradara.

ASGITTARIUS (Nov 23–Dec 22) Boya a le pe o fun irin-ajo, maṣe pe pupo lohun; irin-ajo na a si jasi rere fun o.

CAPRISCORN (Dec 23–Jan 21)

Maṣe na owo Ini inakuna. Oro a-nti-enu-bole le da nkan sile larin awon ebi re, maṣe baraje, gbogbo re yio si dara.

# Tisa Aguda Le Awon Omolewe Jade

IJEBU-ODE—Awon omolewe Obinrin mesan ti nwon nko eko ni ile-iwe giga kan ti awon ijo Ṣosi Aguda ti nwon npe oruko re ni Our Lady of Apostles' College ni iroh n kan Ele–Ofe wipe nwon le nwon jade wipe ki nwon mo lo si ile ebi won fun iwa alaigboran ti nwon hu.

Onirohin wa ṣe alaye fun wa wipe ni oru ojo ose ti o koja yi ni awon omobinrin ile-iwe na gbo wipe nwon fe ṣe iworan sinnima (cinema) kan aladun ni igboro; lehin igbati nwon ti je onje ale tan, ti oga ile-eko na paṣe fun olukaluku pe ki nwon lo dubule, ni awon mesan na ba yo jade ti nwon si fo iganna lo s'ode lo wo iran na.

Enikan ninu awon tiṣa won ni o lo so fun oga ile-iwe na, Rev. Mother F. Culvert, on na si yo kelekele lo si ibi sinnima na, o si ba awon omobinrin na nibe nibiti nwon gbe ti ngbadu ere iran na.

# Alakoso Ivory Coast Ni Ilu Oyinbo



**Awora yi ni eyiti Alakoso ilu Ivory Coast, Ogbeni Houphouet–Boigny, gba ni ilu Oyinbo lojo ti Ajir'oba ilu gesi, Ogbeni Harold Macmillan se aseye pataki kan fun un. Ajir'oba paapa ni o wa ni apa osi aworan na. Aseye ojo na dun, o si larinrin.**

## Bassy Elese Nlo Si Germany

EKO—Irohin kan kan awa oniwe irohin "Eleti–Ofe" ni ana wipe Ogbeni Hogan King Bassey, A-bese-ku-bi-ojo, ati Jegede lo si ilu Germany ni ana, Jimo; Ogbeni Hermann Krause, baba'sale awon omo egbe elese ilu Germany ni o fi iwe pe won wipe ki nwon wa be ilu awon wo.

A gbo wipe ti nwon ba de ilu Germany na nwon a fi oju kan awon omo elese ilu na ati Ogbeni a-bi-ese-ku-bi-ojo kan ti nwon npe ni Max Schmeling eniti gbogbo agbaiye ti mo pelu ese re.

A ko mo igbati awon arakunrin meji na a pada bo si Nigeria. Oko a refo o !

# Eko Akete ILE OGBON (4)

**(Lati owo Olalekan Onatade)**

GẸGẸBI mo ti sọ fun nyin ninu iwe-itan mi akọkọ wipe awọn Oyinbo Faranse (French Company) ni Ẹhingbẹti l'Eko ni awọn Oyinbo kinni ti o kọkọ nta ọja ni ori-pẹtẹsi ni ilu yi. Orisirisi ọja ni nwọn si nma ta nibẹ; ọdọ wọn ni nkan mimu bi tii (tea), koko (cocoa), ti-atẹjẹsẹ (tonic wine), ṣuga, ewe-taba, siga ati awọn nkan bẹẹbẹ.

Owo kekere ni e si nra awọn ọja nwọnyi lọdọ wọn nigba atijo. Nkan ti o jẹ ki o dabi ẹni wipe awọn Oyinbo yi nikan ni o nta nkan onje awọn Oyinbo nigbana ni wipe awọn Oyinbo oniṣowo yoku, awọn nkan bi aṣọ ni nwọn tẹramọ fun tita larin awọn enia wa, a tipe diẹ tilẹ ni awọn enia wa paapa ti o njẹ onjẹ Oyinbo nigbana.

OYINBO ATIJỌ

Ẹ jẹ ki nda orukọ diẹ ninu awọn Oyinbo onisowo igbani fun nyin: awọn bi Oyinbo Niger Coy., Jurgens, John Walken, John Holt, MacLiver, G. Gottschalk (Oyinbo ọlọwọ) Trading Association of Nigeria, Lagos Stores, Miller Bros., Africa Oil Nuts., S. C.I.N., Lever Br os., G.B. Ollivant, C.W.S., Patterson Zochonis (P.Z.) S.C.O.A., Nigeria Motors, G. L. Gaizer, J. W. Jackel & Co., J. F. Sick, Witt and Bush, London & Kano Trading Company.

H. E. B. Green & Co., ni awọn Oyinbo ti a mọ ni alagbakọ-ile (Building Contractor) nigbana; oke Olowogbowo ni nwọn gbe fi ṣe ile-iṣẹ wọn.

Awọn ti a mọ ni Oyinbo ọlọkọ ti nwọn nmu ọkọ elefin wa lati ilu Oyinbo ni awọn bi Elder Dempster ati Woerman Line. O pẹ diẹ ki awọn ti nwọn npe ni Amẹrika Barber Line to de; awọn Oyinbo onisowo si ni awọn ọkọ ti wọn lọtọ ti nwọn fi nko ẹru wa lati Liverpool; awọn bi Jonathan Holt ati Elizabeth Holt.

Awọn Oyinbo Woerman Line yi, Germani ni wọn, nwọn si nko orisirisi ẹru wọ ilu yi ki ogun Germani (Jamani) to bẹ silẹ ni ọdun 1914. Awọn Oyinbo onisọwo ilu won, awọn G. L. Gaizer ni nwọn mba ko ọpọlọpọ ẹru ti nwọn fẹ ta nilẹ yi. Ti nwọn ba si npada lọ si ilu wọn, nwọn a ko apo ekuro, apo koko pẹlu agba epo lọ si ọhun lati fi ṣe nkan pataki pataki fun tita ni ilẹ wa.

Awọn diẹ ninu ọkọ awọn Jamani yi ti mo le niran orukọ wọn ni awọn bi Wagogo, Wahehe ati Wadai. Ẹgan ni hẹ, awọn ọkọ yi kuro ninu ọkọ-yẹyẹ. Iresi ni o fẹ jẹ ni tabi ẹran agutan inu agba, tabi akara "fidjbọ-poo" tabi ẹran ẹlẹdẹ ọlọra. Ti o ba wa mọ ikoko lati mu dara-dara, wa ri ewe taba gbẹdẹ-gbẹdẹ ninu agba. Ọpọlọpọ nkan ọja ti nwọn nmu wa nigba na, ninu agba ni gbogbo wọn wa titi ti o fi de ibi iṣo ati simẹnti ti a nfi kọ ile.

Ọrọ a nko ẹru sinu agba yi ni o jẹ ki ọpọlọpọ awọn ọmọ Eko lọ kọ iṣẹ akan'gba nigbana; awọn ti o si kọ ọpọlọpọ wọn ni iṣẹ agba-kikan yi ni awọn ara Liberia (ti a npe ni Kurumọ). Nwọn kiṣe ọlẹ rara.

IṢẸ K-ṢẸ MBẸ NI ALAKORO

Gbogbo awọn oniṣẹ lebira nigbana ni nwọn ni lati mọ agba (barrel) yi daradara. Alaru-lebira ti ko ba mọ agba nwọnyi lati gbe tabi lati yi nilẹ ki o mọ yi biri-biri, ko nṣe ẹniti o mọ iṣẹ ṣe, nwọn ki si fẹ pe awọn iru enia ti o ba lọra bẹ sinu iṣẹ ti nwọn ba ri lati ṣe.

ẸRUKẸRU MBẸ L'ẸHINGBẸT

Nitoto, orisirisi iṣẹ ni o mbẹ ni ebute Alakoro; apo ekuro ni o fẹ ru ni tabi agba-epo? Bi o ba si jẹ ẹniti o ni ọyaya, ti o mọ owo ṣe, ti o si jẹ ẹniti kii binu rara, gbogbo awọn ero ti nwọn wa ra ọja lati ilu-oke ni wa ma jẹun labẹ wọn, nipa biba nwọn ra ọja bi aṣọ, ewe taba, ọti, iṣo ati panu-ikọle.

Ko si awọn oni-wayọ nigba atijọ, ṣugbọn awọn ole ati onimọlẹ ni nwọn nṣe iṣẹ-baranda (commission agent) nigba na. Ẹnu won dun, ko si si awọn Oyinbo ile-ọja ti nwọn kole dojukọ ba sọrọ.

Awọn Oyinbo igba na lọhun, bẹni wọn bẹna ni l'o ma jẹ. Nwọn ki mu tẹja mọ teku, nwọn ki si mu teku mọ tẹja. Ti o ba pe awọn alaru laiye igba na, iṣẹ ti o ba fun wọn ṣe ni nwọn a ṣe, ko si ojukokoro lọdọ wọn bi awọn alaru aiye isisiyi ti o jẹ wipe ibiti nwọn yio ri iṣẹ ole ṣe ni nwọn mba kiri.

Nig... mo nsọ itan rẹ yi, awọn ọmọ ti nwọn ba ran lọ si ile-iwe ti awọn ko gb... ẹkọ tobẹ, ti awọn obi wọn si ni owo rẹpọ lọwọ lati fi duro fun wọn lọdọ awọn Oyinbo onisowo, nwọn a mu owo t... iwe-de lọ ti duro fun wọ... Owo diyi nigbana; enikeni ti wọn ba fi adọyọ tabi igba po... duro fun nigbana, Olowo papọ ni a si ọ awọn obi rẹ ma si. O si ni lati sọ ara rẹ d-d- nitori ọja ti nwọn ba fi si, ki o ba ma yise, ki awọn Oyinbo Onisowo ma ba gbe ile ẹbi wọn ta, tabi ki owo ti nwọn ba ti duro fun ma ba jona.

Gẹgẹbi mo ti sọ fun yin ninu iwe itan mi ti ọsẹ keji lọhun wipe ti OJU KO BA TI ẸHINGBẸTI, OJU KOLE TI EKO. Adugbo ti a npe ni Ẹhingbẹti ni ibiti gbogbo nyin mọ ni MARINA loni o si bẹrẹ ni ati gun Kẹrẹni Alarun (Five Cowrie Bridge) leti Magasin Iẹba ile Gomina agba titi ti o fi de ile awọn Oyinbo onisowo ti a npe ni Niger House ni Olowogbowo, Awọn iyoku a npe wọn ni Ẹlẹgbata Marina ati Alakoro Marina, ṣugbọn ibiti a mọ ni Ẹhingbẹti ni mo ti daruko fun yin yẹn.

Bi ọrọ itan di opin ti a nkọ wipe:

Iṣẹ-kiṣẹ mbẹ l'Alakoro,
Ẹrukẹru mbẹ ni Ẹhingbẹti
Gberu mi, sọmi,
Mbẹ l'Ebute-Mẹta.
Ma ma sọ gbogbo rẹ fun nyin nigbamiran.

# ELETI - OFE D'araba

# ELETI--OFE

ANJUWỌN KO ṢE WI L'ẸJỌ

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
28, Kosọkọ Street, Lagos, "ELETI OFẸ," LAGOS

P. O. Box 467 Phone 23370.

VOL XIV. No. 826. SATURDAY JUNE 30,- JULY 6, 1962.


# Atigbe'yawo Ko Ja

NINU iwe irohin wa ti ọsẹ yi, ẹ o ri iwe kan ti Ọgbẹni kan ti o nṣe iṣẹ ninu ile awọn Baba'salẹ Igbimọ Igbeyawo l'Eko kọ si Olotu wa; ninu iwe Ọgbẹni na o mba awọn ọdọ wa lọkunrin lobinrin wi wipe ọrọ a ngbe iyawo kiṣe nkan ṣere-ṣere, kiṣe bi ẹni wipe a nlọ ra adiẹ ninu ọja, tabi a nlọ ṣa ekuro ninu oko.

Awa oniwe irohin ELETI-OFẸ ti kakiri gbogbo ilẹ Nigeria, a mọ bi awọn Hausa, Ibo ati Yoruba ti nṣe gbe iyawo. O si tọ, o si tun yẹ ki a gbe ọgbẹni ti o kọ iwe si wa na lẹsẹ wipe ọrọ a fẹ gbe iyawo ki i ṣe nkan ṣereṣere. Nkan ti o gb'ẹlẹgẹ ni.

## Owo Obe Ni O Soro

Ọpọlọpọ awọn ọmọ wa lode isisiyi ni nwọn ko mọ nkan ti a npe ni ọkọ tabi iyawo. Ti nwọn ba ti ba ara wọn pade lode ariya tabi nile ọti, ti nwọn ti le tiro, ti nwọn si kun atike, ti nwọn si mura bi OKU TI O NLỌ GB'ARO NI POPO, nwọn ti ri iyawo tabi ọkọ niyẹn.

Ẹlomiran ko mọ wipe ninu awa ti a rin kakiri, apanla, adẹtẹ, ọlẹṣa ati oniwa buruku bẹbẹ pọ ninu wa; gbogbo wa ni ọmọluwabi ti a ba ti le ro dẹdẹ, ti a si gba rẹrẹ, ti a kun ete bi bebi-alawo, ti a nsẹ ẹju, ti a nmiri jeje; ọtọ ni baba ti a l'oyun fun ni Oke-Popo, ọtọ ni ẹniti a gbe fun l'Ereko. Nigbawo ni ọmọ alara paapa ti a bi ko ni dagba tan, ti ko ni ma da ile ru?

Oromọ - adiẹ ti ko mọ awodi ni ọrọ igbe'yewo awọn ọmọ isisiyi, iya wọn ni ọmọ aṣa.
Pẹlẹpẹlẹ di ọwọ nyin.

# Iwe Si Olotu

## Ara Awe, E Ku As'hinde

Ẹ jọwọ ẹ gba mi laye lati ki awọn ọmọ ilu Awẹ jakejado ati awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ku asẹhinde iku Oloye wa, Ologbe J. A. Ajao ti o jalaisi laipe yi.

Ajao ṣe iwọn tole ṣe, o fi ilu Awẹ silẹ fun ẹro ehin, agba di ọwọ ewe, igba di ọwọ ẹnyin agbalagba. Itọju Awẹ di ọwọ gbogbo wa. Ki olukaluku ṣe agbara rẹ nigba ọsan, nitoripe oru mbọ ti a ko ni le ṣiṣẹ mọ. Ki Edumare to ti nran ọmọ Awe ati ẹbi Ajao lọwọ loju aiye rẹ ma gbagbe wa o.

Ki a maṣe gbagbe pe bi a s'ore titi ao ku, Ọlọrun Ọba ko fori iku jin ni, bi asi huwa ika titi ao ku Ọlọrun ko fori iku jin ẹnikan; ṣugbọn ki olukaluku sa agbara rẹ nitoripe "Atore atika ikan kegbe".

Mo ki gbogbo ẹgbẹ ati ọgba Ajao, eku asẹhinde, paapa julọ awọn ẹbi rẹ. Ọlọrun tiṣe ọkọ fun opo, tiṣe baba fun alaini baba, ti ṣọ ile nigbati bale ile ba lọ sajo yio ma wa pẹlu yin o.

O di gbere, o di arinnako, o di oju ala, ipade di ọrun alakeji.

Emi ni.
Awe D. A. Ọjẹniyi

## Oro Igbeyawo Ki Se Yeye

Inu wa yio dun bi ẹ ba le gba wa laye ninu iwe "Eleti-Ọfẹ" lati le ma fi ọrọ si awọn ọmọ wa leti l'ọkunrin ati l'obinrin nipa igbeyawo aindi ti nwọn ngbe ati paapa lati ma fi iwe sọwọ si wa fun ibere nipa ngbeyawo silẹ, tabi ohun ti nwọn yio ṣe ki a to legbeyawo sile.

Ekeji ni wipe papa awa ọmọ enia dudu ma ngbeyawo bi ẹniti o lọ ra adiẹ ni ọja, a si tun ma mbi ọmọ bi ẹni lọ ṣa ekurọ ninu oko (Kernel) ti ko jẹ ki a mọ ọmọ-ọkọ tabi ọmọ ale nipa iyipọ ẹjẹ (Blood-Mixture) nitori Adukẹ fẹ Ṣhitu loni ṣugbọn lọ'a yio lọ ṣe iyawo Disu nitori owo, igbawo ni ọmọ ale ko ni ṣalaisi larin wa?
Ara, ẹ ṣọra!

Emi ni,
M. Ọlatunde Sanusi.
Lagos Marriage-Guidance Council.
Eko


# OKUJA WO'LU

NIGBATI ỌJA KO BA TA, TI ẸNITI O RA ỌJA KO TA EYITI O RA, BAWO NI YIO ṢE LE RA OMIRAN. EYI NI OGUN TI ONISOWO LE ṢE TI ỌJA LE FI MA TA

Pẹ IṢU AKARA GBIGBONA.

POLOWO ỌJA RẸ SINU ELETI—OFẸ

## E Ma Ka Iwe Irohin Eleti-Ofe

# Nihin Lohin Ati Nibi Gbogbo

(LATI ỌWỌ AYILUKA)

MA F'ỌRUN YỌ MI

"Ẹfuje," baba ni baba nję. Ninu iwe mi ti ọsẹ yi, o yẹ ki nkesi ẹnyni ti o nkawe mi ki e ba mi kẹdu ọ ọrẹ mi, Ologbe Joseph Adediran Ajao ti o jalaisi ninu ọsẹ ti o kọja yi. Temi pẹlu Ologbe na ti mọ ara wa tipẹ ni opopo Olowogbowo l'Eko, nigbati on wa lọdọ aladugbo wa kan, ABUDALA ni Bishop Street, emi alara paapa wa lọdọ ẹgbọn iya mi, Ologbe Ben Joseph, leti Ṣọṣi Olowogbowo l'Eko kanna.

Mo niran igbati mo ba nmu awọn aburo mi, awọn bi Ọgbẹni Femi (the "HAMMERER") ati Fọlarin Joseph lọ si ṣọbu ti nwọn ni ki Ologbe Oloye na ma ba awọn ṣọ, ti mo ba lọ ra fere ọlọpa (police whistle) ati awọn nkan iṣere ọmọde ni orisirisi fun wọn.

Ni aiye igbana, awa mọ agbalagba lẹgbọn, a si ma nteriba fun enikẹni ti o ba ju wa lọ (ko ba ṣe oṣu kan tabi ọdun kan ni Oluwarẹ fi ju wa lọ) agbalagba ni a mọọ si. Tobẹgẹ ti a fi nma kọrin kan bayi:

Igba fẹnikẹni t ojuwa lọ,
Igba f'ọmọkere jojolo, Igba.

GBOGBO WA L'AJỌ NLỌ

Nigba aiye Ologbe na, ti o di ẹniti o nkọle mọ'le, ti o nra mọto mọ mọto, kii fi oju panirẹ rara. Bi o ba ba ọrọ anu de ọdọ rẹ, a si ṣe anu fun ọ. Ko le enia jade pẹlu agbara ninu awọn ile ti o nfi haya ri. Bi o ti nṣe fun alejo ni o si nṣe fun onile.

Mo gbọ wipe awọn ọmọ'loku na, awọn bi Yeyeṣọrun lati Akurẹ, awọn bi Aderọgba ati Adebayọ nmura gidi lati sin oku Oloye na ni oni-pẹrẹwu: ko bu u, o tọ, o si yẹ ki nwọn ṣe bẹ. Ṣugbọn ki nwọn maṣe gbagbe ọti Ṣẹkẹtẹ ti emi Ayiluka pelu apẹrẹ ẹkọ ati amala pẹlu ọbẹgbẹgiri ti o gbadun. Ko ba ṣe l'Ọyọ ni awọn fẹ lọ sin oku na tabi l'Awẹ ni tabi ni Akinmọrin ni. Ọyọ l'Ọyọ jẹ.

Ẹnyin Ọyọmisi ẹ ku aṣẹhinde. "Ẹfuje", ọrun re Ṣugbọn ki a maṣe gbagbe ọrẹ yi; MA F'ỌRUN YỌ MI, GBOGBO WA NI A JỌ NLỌ. Nitorina ki a ṣe rere ki a to jade laiye.

ỌMỌ-DARA

Ni ana ni emi Ayiluka lọ si Ikẹja lati lọ wo awọn ỌMỌ-DARA-O-DẸJỌ ti a ko si idi ọkọ aropileni. Boya ẹ ko mọ awọn ọlọmọge ti emi Ayiluka npe ni Ọmọ-dara o-dẹjọ yi? Awọn ni awọn ọlọmọge ti nwọn ntọju wa bi a ba wọ ọkọ ofurufu ti a nlọ si idalẹ.

Mo gbọ wipe Alhaji Kan ti nwọn npe ni Alhaji Koguna (ọrọ pọ ninu oruko yi, ọrẹ mi) ti o jẹ igbakeji Minisita alamojuto ibiṣẹ Ijọba Apapọ lọ ṣe abẹwo awọn ọlọmọge yi ni Ikẹja laipẹ yi. Nigbati Alhaji Koguna de ibẹ, kaka ki o dakẹ ẹnu rẹ ki o ṣeju si wọn bi awọn ọga rẹ ti maa ṣe si iru awọn Ọmọ-dara-o-dẹjọ bayi ti awọn si nma ri mu lọ si Kano tabi Kaduna ninu wọn, nṣe ni Alhaji ni awọn ọlọmọge yi ko gbamuṣe to.

O DẸJỌ

Kinla? Ki a mọ gbọ bẹ mọ; awọn tani ko dara? Awọn tani ko gbamuse to? Tabi nitori nwọn ko le LALI sọwọ ati s'ẹsẹ bi awọn ẹlẹha Zaria ati iya onituo Funtua? Iwọ wo ete ati ọmọ-ika ọwọ wọn, wa ri LALI asiko nibẹ, wa si tun ri tiro Oyinbo ni ipenpeju won. Bọya Alhaji Koguna [illegible] ni, ka awọn ra TIRO ati LALI nigbakugba ti ẹ ba fi nkọja ni Kano ni; boya awọn wundia Sokoto ko le kun gbogbo lali ti o wa nilẹ tan, tiro paapa si pọju fun awọn WORINGIDA.

Ẹ tilẹ duro na, Alhaji Koguna na ma tilẹ bu ẹtẹ lu awọn ọmọ ẹgbẹ ọṣelu alakuko alabaṣe rẹ, awọn bi Ọgbẹni Ooirungbọn (Mallam) Dafẹ ati "Awe" Oloye Fadahunsi pẹlu awọn ara Oke Ọya bi meji tabi mẹta ni o gba awọn ọmọge awọnyi siṣẹ. Iyẹn ni wipe nwọn ṣe ojusaju nigbati nwọn ngba wọn?

Ki a mu t'ẹgan kuro, awọn ẹlẹhinju-ẹge yi dara to; bi nko tilẹ mọ, mo mọ bi meji tabi mẹta ninu wọn Se Yetunde ọmọ Lọya Shyngle ni a wi, e ko mọ iwe tabi ko gbamuṣe?

Alhaji Abdul Koguna, bi o ka ba fẹ awọn ỌMỌ-DARA-O-DẸJỌ yi, jọwọ mọ da okuta le wọn, nitori awọn ọlọrọ wọn wa ni London ti awọn nkọ lẹta (letter) si wọn.

---

# "Abo Mi Niyi"



Awotan Ọgbẹni Bruce Tulloh, "ayara - b i - a ṣ a" ti ilu Oyinbo niyi nigbati o pari ere - ije bata maili (six miles) ti o ja nibi mare ije gbogbogboo ti awọn Gẹsi ṣe laipẹ yi ni London. Nwọn ni ko si ẹnikẹni t i o l ẹ yara sare bi Ọgbẹni Tulloh yi ni gbogbo ilu Gẹsi n i t o r i p e ati ere oni buso kan t i d e m e j i, mẹta ati mẹrin gbogbo rẹ ni o nwọ jẹ patapata.

# Eru Aiye Ma Mba Mi (2)

**( Lati owo J. Ola Wins )**

NI nkan bi ọpọlọpọ ọdun sẹhin, ni ọrọ Mimọ Ọlọrun ti laye wa kedere nipa ipo ti awa enia wa larin awọn ẹbi wa, ọrẹ ati ojulumọ wa pẹlu. Ki awa paapa fi oju inu wo, ki a si ma fi ọkan ba ọrọ na lọ. Ọrọ mimọ Ọlọrun ti ẹnu Woli Mika (Mika 7 5—8) wa wipe maṣe gba ọrẹ kan gbọ rara tabi gbẹkẹle amọna kan pa ẹnu rẹ mọ fun ẹniti osun (iyawo) n'ookan aya rẹ. Nitoripe lọjọ ti a wa lode isisiyi iyawo ko bọwo fun iya-ọkọ rẹ mọ, bẹni ọmọ ko gbọ ti iya ati baba rẹ mọ, olukuluku ara ile rẹ ni ọta rẹ". O par rẹ wipe maṣe yọ mi iwọ ọta mi bi mo ba wa n okunkun Oluwa yio wa pẹlu mi, bi mo ba subu, lagbara Oluwa ma dide.

Ẹ wa rioe ki ise nkan tuntun fun wa wipe aiye yi soro. Ara mi! aiye ko ma le, awa enia inu rẹ ni ika, awa ẹda paapa ni aiye, ko si aiye kan nibi kan; nyin ati emi na ni aiye, awa na ni a si soro.

Nigbati ẹiyẹ kan ti o ti ngbe arin awọn enia ni aiye atijọ fun ọpọlọpọ ọdun. Ṣugbọn iwa ọmọ araiyẹ le, ni ẹiyẹ yi ba li awọn ẹda silẹ o wa tun nsọ fun awọn ẹgbẹ rẹ wipe "aiye soro! aiye soro!! aiye soro".

Ipo ti aiye wa yi wa ṣe elẹgẹ pupọ, ṣe awọn ni nwọn wipe ki ole lọ ja, ni ẹsẹkanna nwọn si ti tun tọ oloko lọ lati lọ sọ oko rẹ nitori ole mbọ wa ko iṣu rẹ. Oju aiye ni ẹnyin na nri yẹn o.

Ọgbẹni kan sọ wipe "maja-maca ni ile-aiye; oju ogun paraku ni ile aiye" ẹniti o ba ri jẹ inu aiye ko ni dun si, enia bi aparo ni aiye nfẹ.

Nigbati iwọ ba nsọ otitọ inu rẹ jade fun wọn, awọn yio si ma pa'rọ fun ọ. Ani ọrẹ paapa kọ si mọ. Kini o nṣe iku pa ẹda ti oju ọrẹ lọ? Mo sọ fun ọrẹ mi wipe ọmọbinrin kan wu mi, mo fẹ fi ṣe aya no mu ọrẹ mi atata na lọ si ibẹ; nigbati akuro nibẹ o sọ fun mi gbangba wipe, "nitotọ ọmọ na dara o, ṣugbọn idile wọn ko dara ki nyara lọ kọ si lẹ."

A ki si kọrọ si ara wa lẹnu; nigbati o di ọdun kẹta ni ọrẹ mi yi gbe ọmọ binrin na ni arede, ṣe ẹ oju aiye lode tabi ẹ ko ri

Bẹ na ni ẹnikan fi ile kan lọ mi ni ọna Itirẹ,mo sọ tọ ọrẹ mi lọ moko-fun. O ni ki ro, wo dada o. Bi o ti di ọjọ kẹfa, ọrẹ mi de, o ni jibiti ni awọn fẹ lu fun mi. Ọlọrun ni o yọ mi ti mo wa fi lọ on. Ṣe ni mo ba ja'wọ-ja'sẹ kuro ninu ọrọ ilẹ na Ẹnyin Onkawe Eleti-ọfẹ, emi ni ti nyin nitotọ, ọrẹ mi ti kọ'le sori ilẹ na loni, o di meji.

Mo tun fẹ ṣe oowo; mo tun kọja aye mi, mo tun tọ ọrẹ mi kan lọ. Mo sọ fun wipe mo fẹ ṣ'owo, nitori ọja ta ni ilu bayi-bayi. Ọrẹ mi ni ọja ma ti fọ nisisiyi ori lo yọ mi ti mo wa sọ fun on. A ṣe ọrẹ mi ntan mi jẹ ni. K'awi-k'afọ ọrẹ mi mba oowo nalọ rabidun nisisiyi. Melo ni ki a ka ninu iwa ọmọ aiye? Aiye mu tirẹ wa, ki nfi emi pamọ, aiye ti ki bani de ibikan ti wahala ba de, iye ti ba ni wa ti ki ba ni boo aiye toto funun! aiye ti nṣi enia lọna. Aiye akamara.

(Koi ti pari)




**HINDU SANKARA'S**

**Religious Art Jewelleries**

Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers, Kavachas. Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

*Enclose 4/- money order by Air Mail for Catalogues and Literature.*

**HINDU SANKARA, 22 Montpelier Row, Blackheath, London, S.E.3, England**


## E ma ka Iwe Irohin ELETI-OFE Losose

# A Tun Pade!



**Aworan yi ni igbati Eyesorun (Olori) Oba Deji Akure lo be ile-ise ti o ti ko ise a-ntoju alaisan (Nurse) ni Moorfields Eye Hospital, London, wo, ti on ati awon meji omo ilu Nigeria ti nwon nko ise lowo nibe gba. Eyesorun ni o wa larin, Yetunde Lakanu ni o wa ni apa osi pelu Iyafin Yewande Oredola Oke ni o wa ni apa otun.**

# Cash Bonus For Family Doctors

## "Star Doctors" To Get Merit Pay

( By Our London Correspondent )

LONDON—Out here, there are many family doctors who are up-to-date with their jobs and always giving their patients the most up-to- date treatments. These doctors are to get a cash bonus under a new scheme announced recently by the British Health Minister, Mr. Enoch Powell, during a debate in the House of Commons.

How they will get the money has not yet been worked out, but the new scheme will cost British tax-payers about £250,000 a year share-out for these people who take the trouble to keep up with the latest medical discoveries.

According to the Ministry of Health, about one in nine of the 23,000 family doctors now in the British Health Service bothers to take up refresher courses.

### MERIT PAY

So a share-out on this basis would give each "top doctor" an average of about £100 a year.

Another plan is Merit Pay under which between 500 and 1,000 "star doctors" would be picked out and each would be eligible for an additional merit payment of not less than £10 a week. This scheme will also cost British Health Service another £500,000 a year.

This "star award" scheme was a recommendation of the Royal Commission which investigated Health Service pay, and this move is likely to meet strong opposition from the members of the British Medical Association when they meet in Belfast next month.

Mr. Powell, the Health Minister also announced a further £750,000 a-yea r pay-out for doctors with between 1,000 and 1,500 patients on their lists.

As there are few doctors with fewer than 1,000 patients in their lists, it means that all doctors in British Isle will share in this hand-out and each doctor will receive an average of £33 a year more pay.

## Free From Hunger

ROME — The World Veterans Federation, a 20-million-member international organization, has agreed to sponsor the employment of a poultry expert to work in West Africa for one year. The sponsorship is a contribution to the "Freedom from-Hunger Campaign" of the Food and Agriculture Organization.

Campaign officials said the donation is valued at 20, 000 dollars and will cover salary and travel expenses.

"The duties of the expert", an officials said, "will be advise governments and private producers in West Africa on poultry-improvement projects, and to work with WVF member association there on projects they may wish to undertake. He will work under the supervision of F A O's poultry-production section and will co-operate with a poultry expert".

## Problem of New BRITISH IMMIGRATION CONTROLS

LONDO — Mr. David Renton, Britain's Minister of State at the Home Office said that immigration controls which were going to be introduced when the Commonwealth Immigrants Act became law on 1st July were "designed to make the control as little irksome as possible to Commonwealth citizens arriving in Britain".

Speaking at London Airport at the end of an inspection tour of ports and airfields in Britain, Mr. Reaton said that Britain would continue to welcome Commonwealth citizens He regarded the controls as a necessity. "But we hope that Commonwealth citizens arriving here will not be delayed unduly by examinations. They will be carried out as speedily as possible".

Mr. Renton said that the new controls at London Airport had necessitated increasing the immigration staff by twenty-one per cent. "We will have 140 officers working here and the number of officers working at British ports have been increased from four hundred to 479".

# Domestic Science Students



Her Majesty Queen Elizabeth the Queen Mother taking tea with some of the students when she visited the National Training College of Domestic Subjects in London, England. Centre is Miss Irene Fisher from Warri, Western Nigeria.

Miss Fisher will be returning to Nigeria on completing her studies this summer, and will be entering the catering industry.

# Irohin Soki

## Lati Owo Ayiluka

### Oku Malu

Oku-malu, Ayiluka ni on kii jẹ oku adiẹ ambotori oku malu. Mo gbọ wipe awọn kan ni ilu Agba leti Ishelu lẹba Abakaliki ni Ipinlẹ IlaOrun ni awọn fẹ ṣe aṣeyẹ kan ninu abule wọn, ni nwọn ba mu ẹran oku-malu, ni nwọn fi se ọbẹ fun awọn ti o wa si ibi aṣeyẹ na. Enia marun ni nwọn ku patapata ninu awọn ti nwọn jẹ onje aṣeye yi; awọn miran si wa loju iku bi mo ti nkọ irohin yi.

Awọn ọlọpa nu nṣe iwadi ki lo fa sababi yi lọwọ.

### Apa'nia

Mo gbọ wipe awọn oniṣegun kan wa ni Ipinlẹ Ila-Orun ni agbegbe Kalaba nwọn fẹran awọn obinrin ti o ba nrọbi lọwọ lati ba lo pọ. Emi ko mọ ipinlẹ apa ilu ti nwọn ti wa gan ni Nigeria, ṣugbọn mo gbọ wipe kakiri apa Kalaba ni nwọn fẹran lati ma ṣe irufẹ iṣẹ bẹ.

Laipẹ yi ti Minisita alabojuto eto ise Ilera, Oloye B. C. Okwu lọ ṣe abẹwo ipinlẹ na, ti o si de agbegbe Kalaba (Calabar), o ni igbati on de ile igbẹbi awọn aboyun ti on ri

awọn aboyun kan ti nwọn wa ninu irora nigbati nwọn nrọbi, ti nwọn lọ si ile awọn onișegun ibilẹ (native doctor), KI A DAKẸ, KI A SI S'EDE KI A TO MA SỌRỌ ni nkan ti oju awọn aboyun yi ri nibẹ.

Oloye Okwu ni on yio da ni imọran fun Ijọba wipe ẹnikẹni TI O BA BA ABOYUN LO PỌ NIGBATI O BA NRỌBI LỌWỌ, ẸJỌ APA'NIA ni ki nwọn be oluwa rẹ ro. Emi Ayilu-

ka l'arumọ aba rẹ na. Ọrọ re e, ẹnyin ara wa.

### Ehin Alarede Da?

Mo gbọ wipe obinrin alarede kan ti o ti ba onitirẹ kan ṣe igbadun faaji ninu moto-ayọkẹlẹ lọ si ọna Shomolu pade agbako kikọlu-enia kan ni Campos Street l'Eko nigbati nwọn npada bọ wa si ile.

Ninu agbako ijamba moto yi meji ninu ehin ẹnu alarede na yọ silẹ, ṣugbọn itiju "kini-ka-ti-gbọ" ko jẹ ki o le duro mu nwọn.

Ẹnyin ọkọ-alarede, ẹ wo ehin ẹnu iyawo yin boya o wa loju titi ni Campos.

### Olopa Ihamo

Ọrẹ mi, ṣe ẹ ti tun gbọ wipe awọn kan ti tun njade kakiri nisisiyi ti nwọn npe ara wọn ni ỌLỌPA IHAMỌ? Boya nwọn ko ti de ọdọ re. Nwọn le wa ni arọ kutu-kutu tabi ni ọganjọ oru. Ibikibi ni nwọn le wa ẹ lọ.

Nwọn le paṣẹ fun ọ wipe Adekoye ni ki o ma ṣe mu iyawo rẹ lọwọ ki o gba Kutuwenji lọ lẹba ilu Tapa, iwọ ati eti rẹ nikanṣoṣoṣo.

Ti nwọn ba wa ba ọ, ki o sọ wipe ki nwọn lọ fi iwe waranti wọn han emi Ayiluka l'Eko nitoripe oniwayo ni wọn. Tabi bẹkọ Ọgbẹni Harley, Ọlọpa a-bi-ṣokoto-pọnbe?

### Owo Titun

GBOGBO awọn obinrin ti ọkọ wọn fun ni owo-atijọ ni owo ọbẹ lana ni oju wọn ri enmọ l'ọja Ereko ati ni ita Faji nitope ọpọlọpọ awọn iya-ẹlẹja ni o kọ ọ, nwọn ni owo-tuntun ni awọn nfẹ.

Nwọn ko parọ rara nitoripe emi Ayiluka gbọ wipe lẹhin ọjọ ọsẹ ola (Sunday) nwọn ko ni gba owo yi ninu ile taja ti sobu mọ, ṣugbọn gbogbo ẹniti o ba ni owo atijọ yi lọwọ ki nwọn tete mu lọ si ile ifowo pamọsi (bank) fun iparọ si owo-tuntun, nitoripe awọn alaṣẹ ile-owo Ijọba ni lẹhin oṣu September ẹnikẹni ki yio le parọ awọn owo

nwọnyi lofẹ mọ.

### AWỌN "ẸLẸHA" APAPANDODO NJADE DIẸDIẸ

IBADAN—Boya nigbati o ba nka iwe irohin "Eleti-Ọfẹ yi lọwọ, a le tun gbọ wipe Dokita Majẹkodunmi, Aṣoju Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun tun da diẹ silẹ ninu awọn oṣelu ti nwọn fi iwe-

ihamọ sọ di "ẹlẹha" apapandodo kakiri agbegbe ipinlẹ na, nitoripe ni ọrọ ọjọ'Ru (Wednesday) ni ijọ́ ti nwọn da awọn mẹrin silẹ ninu wọn.

Ninu awọn mẹtala ẹ nwọn dasile ni Oloye T.A. Odutọla, Ọgbẹni Ọja Ijẹbu-Ode, Ọgbẹni Kensington, Momọ, ẹniti nwọn fi aga fọ lori ninu ile Igbimọ, Ọgbẹni Fani Kayọde, Olori alatako ni ile Igbimọ Iwọ Orun, Oloye S. O. Ighodaro, minisita alamojuto eto Idajọ tẹlẹri, Oloye Mọjidi Agbaje ati awọn enia bẹẹbẹ.

Irohin ta si wa leti wipe ọpọlọpọ awọn ti nwọn ko ti da silẹ ninu ni ihamọ yi ni nwọn yio pe lati wa sọ t'ẹnu wọn ninu ọrọ iwadi ti Adajọ Coker fẹ berẹsi ṣe iwadi ninu osu ti mbọ yi.



Aworan yi ni ti Ogbeni Humphrey Uwaeghute, ara Okigwe ni I l a orun Nigeria, ni ile-iwe giga fun ise agbe nibiti o ti nko ise bi a ti ntoju awon eran-osin ni ilu Oyinbo. Akeko yi ni ti on ba pada si Nigeria ise olukoni ni ile-eko giga ti Nsuka ni on fe mo se ise na ti on ko.

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28 Kosoko Street Lagos Box 467 Phone 23370; OLOTU: OLA. ONATADE, 15, Kosoko St., Lagos,